# IPINNU AJO ISOKAN AGBAYE LAROWO-TO RE



United Nations

## IJABO ISE LATI ODO AKOWE GBOGBO-GBOO

Laarin aaaota odun sehin, Ipinnu Ajo Isokan Agbaye ti di ofin ati agbekale ajumosepọ to gun rege. Lehin ayipada lorisi-risi to ti waye, gbogbo ifikunlukun lori ifowo-sowopo ti a ti la kale ninu Ipinnu Ajo yi, lo duro sinsin. Loni, Ipinnu (ifohun-sokan) wa je gbongbo fun ifowo-sowopo lagbaye lorii wiwa alaafia ati ilosiwaju.

Ipinnu Ajo yii se alaye awon ohun ajosepo, ajoro ati awon ohun ti a n lepa , bee naa lo tun fi aaye sile fun gbigbo ara eni ye, yekeyeke ati imuse se lori awon igbese wa lakotun. Erongba awon to se agbekale Ipinnu Ajo yii - ni lati se idaabo-bo awon iran to n bo, lowo ogun jija, ki won fi okan awon eniyan bale ninu igbagbo won ati ninu eto omo eda lawujo, lati se agbekale awon ona ti ijoba se tiwa-n-tiwa fi le fidi joko ati lati wa ilosiwaju ninu igbe àye rere pelu irorun lawujo - awon ohun wonyi di dandan lati tera mo fun wiwa loore-koore bi igba se n yipo.

Loni, gbogbo agbaye ti lu jara won A ti rii pe gbogbo ilakaka ifowo-sowopo kaakiri agbaye ni o ti ye ara wa, eyi ti a gbodo jijo gbaruku ti. Bi a ba fe gbogun ti awon ohun ti o n da yanpon - yanrin sile, a gbodo sowopo ji giiri si ojuse wa.
Bi o ba je wipe a ti setan lati wojutu si awon ohun ti o n da rogbodiyan sile lagbaye loni, igba yi nikan ni a to le ni ilosiwaju ti a n lepa lakotun.

Ipinnu (ifenuko) je aseyori to buyaari fun omo eda. Akosile ohun itan ti ko se fowo ra to je ohun amuyagan ati aridunnu.

Ajodun aadota odun je ayeye ti a gbodo fi ronu lori awon ohun ti a ti gbese sehin pelu atupale ero tuntun. Bi awon eniyan Ajo Isokan Agbaye se n kominu lori ojo iwaju, beeni Ipinnu (ifenuko) je gbongbo ti o fini lokan bale lati maa te siwaju lai beru. Idi pataki ti a fi gbe Ipinnu jade gbodo maa je wa lokan gidigidi. A gbodo maa so agbara dotun lati koju awon isoro ojo iwaju. Awon erogba wa lori Ipinnu je atokun fun awon iran to n bo lehin lati gbaradi fun ileri lati sàkitiyan lorii wiwa isokan omo eda.

Boutros Boutros-Ghali
Akowe Gbogbo-Gboo fun
Ajo Isokan Agbaye.

# Ipinnu Ajo Isokan Agbaye

## Larowo - To Re



A Translation of the "United Nations Charter at your finger tips" Into Yoruba

AJO ISOKAN AGBAYE
EKA FUN AKEDE IROYIN
NEW YORK

| | | |
|---|---|---|
| IFAARA | - | Awa eniyan Ajo Isokan Agbaye |
| APA KINNI | - | Awon koko ohun ti a ni lokan ti a si n lepa |
| APA KEJI | - | Omo Egbe |
| APA KETA | - | Awon Eka |
| APA KERIN | - | Igbimo Ipade Gbogbo-Gboo |
| APA KARUN | - | Igbimo Eleto Aabo |
| APA KEFA | - | Pipetu si aawo iha Pasifiiki (Pacific) |
| APA KEJE | - | Igbese lorii ohun to fe tepo si aala alaafia, da Rogbodiyan ati ruke-rudo sile. |
| APA KEJO | - | Eto elekun-n-je-kun |
| APA KESAN | - | Eto oro-aje lagbaye ati ifowa-sowopo lori awon Ohun amuludun. |
| APA KEWA | - | Igbimo Eto Oro-Aje ati Awon ohun amuludun |
| APA KOKANLA | - | Agbejade ito-pinpin lori awon orile-ede ti won ko tii gba ominira. |
| APA KEJILA | - | Eto Ajosepo-Sakoso |
| APA KETALA | - | Igbimo Eleto Ajosepo-Sakoso |
| APA KERINLA | - | Ile-Ejo Agbaye |
| APA KEEDOGUN | - | Olu Ile-ise |
| APA KERINDINLOGUN | - | Ipese Fun Awon Ohun Olokan-o-jokan |
| APA KETADINLOGUN | - | Eto Idaabobo atowoda wo |
| APA KEJIDINLOGUN | - | Atunto |
| APA KOKAN-DIN-LOGUN | - | Ajumo fenuko ati ikowo bowe. |

## 1 KINI IPINNU?

Ipinnu je agbekale awon ilana ati igbese lori awon koko ohun pataki ati idi ti Ajo Isokan Agbaye fi je jade lori ohun ti won n lepa. O tun je adehun ti orile-ede kookan fowo si, ti won si gba lati bowo fun nigba ti won di omo egbe Ajo yi. Ipinnu yi pin si apa mokan-din-logun pelu aadofa le eyokan atiku. Ogidi eda akosile yi wa ni ile isura Ajo Isokan Agbaye.

Ase ti a fi gbe Ile-Ejo Agbaye dide, bi o tile je pe, o da duro, sibe-sibe o jekan lara eka Ipinnu yi. Orile-ede yowu ti o ba di omo egbe Ajo Isokan Agbaye ti di okan lara ajumose po ase ile-ejo Agbaye.

## 2 IGBA WO NI AGBEKALE IPINNU YI JADE?

Akojopo ati agbejade Ipinnu yi waye ninu odun 1945, ti won si fowo sii pelu : Ninu osu Kerin Odun 1945, aadota orile-ede pade ni ilu Şan Francisco lati se asekagba agbekale Ipinnu ti yo gbe Ajo Isokan Orile-ede agbaye kale. Lehin ijiroro fa ki n fa o, won gbe Ipinnu yi jade fun ifowo si ni ojo kerin-din-logun osu kefa odun 1945. O di ilana ti o pon dandan lati faramo ni ojo kerin-le-logun osu kewa odun 1945. Lati igba naa ni won ti ya ojo kerin-le-logun osu kewa odun soto lodoodun fun ayajo ajodun Ajo Isokan Orile-ede agbaye.

## 3 Kini Awon Koko Ojuse Ti Ajo Isokan Orile-Ede Agbaye gbe Jade Ninu Iwe Ipinnu Won?

Awon koko ojuse Ajo yi ni lati:

* Teramo wiwa alaafia ati aabo to nipon ni kaakiri agbaye.
* Wiwa idagbasoke ajumose po olore sore láarin awon orile-ede gbogbo.
* Lati jumo gbaruku ti iranlowo lorii igbe aye irorun fun awon eniyan ati lati teramo ibowo fun eto ati ominira enikookan lawujo ati pelu pe
* Ki Ajo yi je ogba ajara lorii bi won yo se gbaruku ti awon orile-ede fun aseyori awon nnkan wonyi ti won n lepa.

## 4 Kinni Ipinnu so nipa ominira Orile-ede?

Atiku keji Ipinnu Ajo yi so pe, Ajo Isokan Orile-
Ede Agbaye duro lori ominira dogba-n-dogba fun gbogbo omo egbe, kii se ijoba Agbaye. O n pese gbogbo awon ohun to le yanju awon isoro pelu gbigbogun ti ohun yowu to le je edun okan fun omo eda. Ko si akosile kankan ninu Ipinnu yi ti o fun Ajo Isokan Agbaye lase lati da si oro to je mo isele abele orile-ede kan-koda ko faye sile fun orile-ede yowu lati gbe oro bee wa sinu Ajo Isokan Orile-ede fun pipetu si.

Gedegbe ni akosile yii da duro ninu iwe Ipinnu lorii oro ti o ba jemo oro abele. Sugbon sa, Igbimo Eleto Aabo lagbara lati da si isele yowu ti won ba fura si pe, o le da rugudu sile lagbaye tabi je akoba fun alaafia ati

aabo. Bakanna ni eka to ba ye labe Ajo Isokan Orile-ede Agbaye ni eto lati jiroro lorii titapa si eto omo eniyan laarin awon orile ede kan.

## 5 Awon wo ni koko Eka Ajo Isokan Orile-ede Agbaye ti Ipinnu gbe jade?

Eka mefa gedegbe ni Ajo Isokan Orile-ede agbaye ni. Awon ni, Igbimo Gbogbo-Gboo, Igbimo Eto Aabo, Igbimo Eto Oro-aje ati awon ohun amuludun, Igbimo Eleto Ajosepo-sakoso, Ile-Ejo Agbaye ati Olu-Ile-Ise. Gbogbo awon eka wonyi ni won wa ni Olu-Ile-Ise Ajo Isokan Agbaye ni ilu New York ayafi Ile-Ejo Agbaye ti o wa ni ilu Hague ni ile Netherlands.

| | | |
|---|---|---|
| Ile-ejo Agbaye | Igbimo Gbogbo-Gboo | Igbimo Eleto Oro-Aje Ati awon ohun Amuludun |
| Igbimo Eleto Aabo | Olu ile-ise | Igbimo Alajosepo-sakoso |

## 6 Eka wo ni o ko gbogbo omo egbe jo po ati pe kini ojuse eka yii?

Apa kerin ni o so nipa Ile Igbimo Gbogbo-gboo ti o je orisun Ajo yi, ti o si n se abojuto ise awon eka yoku ninu Ajo Isokan Orile-ede agbaye. Atiku Kesan fi yeni pe gbogbo Orile-ede to je omo egbe lo wa ninu Igbimo yi. Igbimo Gbogbo-gboo yi le jiroro ki won si gbe amoran won jade lori oro to ba jemo alaafia agbaye, ayafi aawo to ba waye tabi isele kan ti igbimo eleto aabo ba ti dawole gege bi ojuse re labe Ipinnu. Igbimo Gbogbo-gboo maa n gba ijabo ise wole lati owo awon eka yooku ninu Ajo Isokan Orile-ede agbaye pelu ti Akowe Gbogbo-gboo. Igbimo yi lagbara lati gba omo egbe titun wole ki won si yan Akowe Gbogbo-gboo bi Igbimo eleto aabo ba gbe aba yi wa siwaju won. Ni odoodun ni igbimo yi maa n yan omo egbe titun marun sinu igbimo eleto aabo. Igbimo Gbogbo-Gboo lo n pinnu iye owo ti orile-ede kookan gbodo da fun Ajo Isokan Agbaye ati bi won yo se maa seeto inawo. Ni pato awon lo n sakoso eto inawo.

Igbimo Gbogbo-gboo lagbara lati se ojuse lori isele yowu ti o ba kan Ajo Isokan Agbaye, bii eto omo eda lawujo, eto bi a se n po sii, eto idagbasoke, adinku ilo ohun ose, eto ayika, lilo egboogi oloro nilo kulo, awon ti ogun le kuro nilu (atipo) ofin to ro mo oro oju-omi tabi afefe ni soki. Igbimo yi lo n dari eto ifowo-sowopo ti won si n lepa ilosiwaju ninu ajosepo laarin gbogbo ijoba lagbaye.

Gbogbo Ipinnu Igbimo Gbogbo-gboo ko ni ase, sugbon o duro gege bi amoran fun awon orile-ede lati tele. Sugbon sa, Ipinnu Ile Igbimo yi se pataki pupo lawujo agbaye. Nile Igbimo yi ni opolopo adehun ti n je jade ti iye awon orile-ede to ye ba ti fowo sii ki o to le sise lori awon orile-ede naa labe ofin Agbaye.

## 7 Eka wo lo ni ojuse tito pinpin alaafia ati aabo, ati pe omo egbe melo lo ni?

Gege bi Apa karun ti so, Igbimo eleto aabo ni eka to n bojuto wiwa alaafia a ti aabo lagbaye. Gbogbo awon orile-ede ninu Ajo Isokan Agbaye ni won gba lati maa tele ilana ipinnu Igbimo eleto aabo.

Igbimo eleto aabo lo maa n gbiyanju lati petu si rogbodiyan, ede ahiyede to le waye laarin orile-ede kan si ekeji bi oro naa ba fe kolu alaafia ati aabo agbaye. Nipase eyi, won a pe ijoko ifikun-lukun tabi ki won ran iko olofin-toto tabi ki won fi iko ajagun olulaja ranse. Bakanna ni Igbimo yi tun lagbara lati fi oruko awon orile-ede ti won fe di omo egbe titun ninu Ajo Isokan Agbaye sowo si Ile Igbimo Gbogbo-gboo tabi eniti won ba fe yan si ipo Akowe Gbogbo-gboo. Bakanna ni won tun n pawopo pelu Ile-Igbimo Gbogbo-gboo lati yan awon adajo Ile-ejo Agbaye.

**Omo** Igbimo meedogun lo wa ninu igbimo eleto aabo. Awon Orile-ede marun ti won je igi lehin ogba Ajo yii je omo igbimo - awon ni - ile China, Faranse (France), ile Rosia, Ile Geesi (United Kingdom) ati ile Amerika (United States) Awon orile-ede wonyi ni alagbara lasiko ogun Agbaye keji. Awon orile-ede mewa miran ti won kii se igi lehin ogba ni Ile-Igbimo Gbogbo-gboo tun yan fun odun meji-meji lati je omo Igbimo eleto aabo (wo ibeere kokan-le-logun).

## 8 Kini ase Kannpa ati pe, ibo lo ti jeyo ninu Ipinnu?

Igbimo eleto aabo lo ni ase kannpa. Agbejade yowu ti o ba waye ti okan lara awon Orile-ede alagbara ba kuna lati fowo si, maa di otubante. Oro "Kannpa" ko si ninu iwe Ipinnu, sugbon o jeyo ninu Atiku keta-din-logun, ti o fun awon orile-ede alagbara maru. lase ajumo dibo-po yii, "Ajumo Dibo Po" tumo si ifaramo aba tabi "Ilodi Si". Fun idi eyi, awon Orile-ede alagbara ni agbara ase kannpa.

## 9 Ipinnu wo lo menuba awon ona wiwa ati ifese rinle alaafia?

Apa kefa soro nipa pipetu si aawo lorisirisi ona bii, apejo jiroro, yiyan asoju olupetu si ija tabi iyanju oro labe ilana eto idajo. Igbimo yi le kesi awon orile-ede to n ja lati jo joko iduna-dura laarin ara won tabi ki won se agbejade awon ilana to le pana aawo laarin won fun agbeyewo. Awon ona miran ti igbimo yi fi n petu si aawo ni nipa riran iko oluwadi tabi gbigbe igbimo oluwadi dide tabi ki won ran Akowe Gbogbo-gboo lati jise ipetu soro aawo sibi isele naa.

Apa keje toka si ilo ipa ati awon ona miran, pelu igbese ti o ba ye lasiko ti ruke-rudo ba n lo lowo. Boya iru isele yi le koba alaafia tabi ki awon iko to n ja ma kobi ara si ipinnu igbimo eleto Aabo. Igbimo yi le lo ona ifi ipa bani ja bii gbigbe ese le ilo ohun ose, tita a ti rira awon ohun ija fun awon ara adugbo naa igbese le abasepo ise oro-aje pelu orile-ede naa, ifopin si ijoko asoju orile-ede naa tabi ki won gbe iko ajagun dide lati petu si iru isele yi. Ninu osu kejo odun 1995 iru igbese yi waye lori awon omo egbe

meje, ile - Angola, Iraki (Iraq), Laiberia (Liberia) ile Libiya (Libya) ile Somalia ati ile Yugosilafia (Yugoslavia). Igbimo Aabo fori jin ijoba ile Ruwanda (Rwanda) lorii igbese le ilo ohun ose to waye ninu odun 1994, sugbon won fi ofin de tita ohun ija fun awon ajagun ti kii se ti ijoba lati lo ni ile Ruwanda (Rwanda).

Bakanna ni a rii gege bi apeere pe, Igbimo Eleto Aabo ti gbe awon igbese kan ti ko si ninu Iwe Ipinnu sugbon ti o wa labe awon ilana ese ti won le gbe lati fi dandan tabi oote le awon nnkan ti won ba fe. Fun apeere ninu osu kerin odun 1991, Igbimo yi gbe iko olu sofin-toto Ajo Isokan Orile-ede Agbaye jade lorii tito pinpin kiko omo-ogun ati ohun ija kuro ni aala Iraki ati Kuweti (Iraq-Kuwait). Lehin eyi, ninu osu karun odun 1993 igbimo Eleto Aabo yi fowosi abo iwadi to jade lori oro aala ile mejeeji, ti o si di ofin. Ni afikun Igbimo yi kanna pinnu lati gbe iko oluwadi agbaye kan dide lati pe gbogbo eniyan ti o ba tapa si ofin ilana eto omo eda lagbegbe Yugosilafia (Yugoslavia) tele ri lejo. Iru iko iwadi yi kanna waye fun ile Ruwan-da (Rwanda) ninu osu kokanla odun 1994. Gbogbo awon igbese yi waye labe Apa keje ninu iwe Ipinnu.

O tun se pataki lati se ayewo Atiku kokan-le-laadota ninu iwe Ipinnu ti o so pe, Orile-ede kan ti o je omo egbe ni eto lati gbaradi fun idaabobo ara won bi orile-ede miran ba kolu won, ki Igbimo Eleto Aabo Agbaye to da si oro naa.

## 10 Kini awon igbese ti iwe Ipinnu fi lele lorii wiwa alaafia ti won ko tii sise le lori?

Iwe Ipinnu duro lorii aabo ti o nipon fun gbogbo-gboo, lona to fi je pe bi orile-ede kan ba koju ija si ekeji, iru igbese bayi je afoju-di si gbogbo iko agbaye. Eyi tumo si pe rogbodiyan nibi-kibi je ona titapa si aala alaafia gbogbo aye. Ati wi pe, gbigbe iko Ajagun orile-ede agbaye dide, maa je ikilo fun orile-ede ti yo fe gbogun dide.

Gbogbo awon orile-ede lo gbodo pese omo-ogun pelu atilehin ohun ija fun Igbimo Eleto Aabo lorii wiwa alaafia ati aabo ni agbaye. Iko awon ajagun yii maa wa labe ogagun kookan fun awon orile-ede alagbara ninu Igbimo Eleto Aabo. Ojuse won ni lati maa gbaruku ti igbimo yii pelu amoran to danjiga (to peye) fun ifese alaafia ati aabo to nipon rinle sinsin. Sugbon sa, lati igbati won ti da Ajo Isokan orile-ede Agbaye sile, won ko tii lo ilana igbese yii - Atiku iketa-le-logoji ati iketa-din-laadota ko tii di lilo.

## 11 Awon Ipinnu wo lo soro lorii eeto ilaja?

Eeto ilaja ko jeyo bii koko kan ninu Iwe Ipinnu. Ona kan pato ti Ajo Isokan Agbaye n gba lati fi gbe alaafia kale ki won si petu si rogbodiyan ni lilo a kojopo awon ajagun agbaye. Gbogbo awon omo egbe Ajo yi lo n da iko ologun won sinu ajagun agbaye labe ase Akowe Gbogbo-gboo. Iko awon Ajagun yii lo maa rii pe won petu si aawo, dawo ogun duro tabi ki won se eeto adehun fun awon to nja.Pipetu si aawo lode oni, ko fi bee dan-moran-in , nitori pe, rogbodiyan ko duro soju kan, egbinrin ote ni, bi won ti n pakan, ni omiran n ru were. Ija aala ile tun po ju ti orile-ede si orile-ede lo. Lasiko awon isele to ti waye a ti ri daju pe, opolopo, ibiti awon olulaja lo, ni ko si adeun tabi ijoba kan pato to le pase.
Ni saa ta wa yi, awon ilana ilaja to n waye ni lati da iko ajagun mejeeji duro, agbekale adehun, abojuto eto idibo, ipolongo ibowo fun eto omo eda, didawoo lilo awon ohun ose ogun duro, ekose fun awon alase olopa, aabo fun ogooro ara ilu ati pipese onje pelu awon ohun amulo fi soso ara fun awon ti ogun n ba ja.

Akowe Gbogbo-gboo ninu akole ijabo re - "Eeto Fun Alaafia" ninu odun 1992, gbe opolopo aba jade lati le jeki ilana tito pinpin ati ifese alaafia lele, ti Ajo Isokan Agbaye n lepa gunle rege, paapaa julo bi eto inawo se maa gun regi lori awon awolu isele pipana rogbodiyan.

Fun apeere o beere fun idasile owona fun eto ilaja lati fi bere ise lakotun. Akowe Gbogbo-gboo da eka eto inawo yi sile ninu osu kejila odun 1992 pelu aadojo milionu Dola, sugbon ko tii ri owo naa kojo tan. Won tun kesi awon eka ijoba orile-ede kookan lati se atilehin lorii pipese owona fun iko awon ajagun won. Eto idanileko, ati ekose to ye kooro fun iko awon olulaja, ologun ati awon eeyan ilu ti yo kopa. Imu-gbooro agbekale ilana awon ohun eelo ati iko ajagun gbodo waye.

Aba miran ti o tun jeyo ninu "Ilana Eeto Fun Alaafia" ni igbedide iko ajagun ti yo duro ni sepe fun pipe pajawiri. Ninu osu kejo odun 1995, awon orile-ede meta-din-laadota pese iko omo-ogun won sinu iko yi ti yo fere to egberun lona marun-lelogota omo-ogun. Iru iko Agbaradi-Jagun yi a wulo fun pipana rogbodiyan pajawiri, ti won si le yara ko won lo fun pipana isele aburu kan ko to buyaari labe Ajo Isokan Orile-ede Agbaye. Sugbon awon omo egbe gbodo faramo iru igbese bayi ko to waye.

Ninu atejade Akowe Gbogbo-gboo lorii ilana eto yii kanna ninu osu kinni odun 1995 fiyeni pe, opo lara awon rogbodiyan to n waye jeyo laarin orile-ede kookan, ti awon soja ati ologun kopa nibi ti opo eniyan ti sagbako jamba orisi-riisi ti won si ba awon ohun ini ijoba je. Awon isele ti o n waye bayi je mo itoju pajawiri fun gbigba emi la eyi ti apa awon alase ko tii ka.

Akowe Gbogbo-gboo se akiyesi pe, bi o tile je pe awon ilana eto fun Alaafia ti so eso rere, sibe-sibe ko gbodo si idaduro ninu tito pinpin ati ifese mule alaafia. Lara awon ilana eto ti omo egbe gbodo ji giiri si ni eto inawo, agbekale eto ilaja ati pipetu si rogbodiyan pelu ifowo sowopo laarin awon orile-ede kookan.

## 12 Kini Ipinnu so lori eto elekun-je kun?

Iwe Ipinnu yii se ekun rere alaye ninu Apa kejo eto pinpin awon ise ni isori-isori ti elekun-jekun tabi asoju. Awon orile-ede to je omo egbe Ajo gbodo gbiyanju lati yanju ede aiyede ni elekun-n-jekun, ki won to le gbee siwaju Igbimo Eleto Aabo. Eeto yi fun ekun kookan lagbara lati koju isoro ki won si wojutu si edeaiyede to le waye.

Ipinnu ko menuba koko eto lorii pinpin awon orile-ede si isori-isori, sugbon eto yowu to le waye gbodo wa ninu ibamu pelu ilana ojuse Ajo Isokan Agbaye. Lori e, won fi aaye sile fun isori awon orile-ede ni ekun kookan lati gbe igbese ti o ba ye lorii isele yowu to le waye, sugbon iru igbese bee gbodo tona labe eto wiwa alaafia ni agbaye. Gege bi "Eeto wiwa Alaafia" se salaye, awon egbe kan le sowopo lori adehun latowo ara won ki a to da Ajo Isokan Agbaye sile tabi lehin idasile re, fun aabo ati idaabobo ṭabi fun ise idagbasoke tabi ifowo-sowọpo eto oro-aje.

Opo awon orile-ede ni elekun-n-jekun ni won ti bere si kopa ise ajumose-po pelu Ajo Isokan Agbaye. Lara won lati ri "Ajo Isokan ile Afirika, pelu ti iha ila-oorun sahara, ati ile Laberia (Liberia) tabi iha guusu ajosepo okun Atilantiki (North Atlantic Treaty Organisation) ti won sun mo Ajo Isokan Agbaye ninu ise ajosepo lori aabo ofin lati gbegi dina awon aaye ti oko ofurufu ko gbodo gba ni agbegbe Bosinia (Bosnia)

## 13 Ba wo ni Ipinnu naa se pese aaye sile fun idagbasoke oro-aje ati isamojuto ilu?

Ori kesan-an ati ikewaa laa yekeyeke pe Ajo Isokan awon orile-ede agbaye a se igbelaruge osunwon igbeaye to ga, wiwa ojuutu si awon isoro oro-aje ati isamojuto ilu ati ibowo fun eto eda eniyan. Eka ti won gbe kale lati se aseyege awon erongba wonyi ni Igbimo eleto oro-aje ati Isamojuto - ilu.

Igbimo Eleto oro aje ati Isamojuto ilu lese agbekale ise iwadii ati ijabo ni ilana si eto oro aje agbaye, isamojuto, asa, eto eko, ilera ati awon oro miiran to nii se ninu oro yii, ki won si gbe aba won kale niwaju Igbimo Gbogbo-gboo Ajo isokan orile-ede agbaye. O tun le pe ipe fun Igbimo Gbogbo-gboo lati fi oro naa si aaye pataki, ki awon ijoba ati eniyan le ta kiiji si awon isoro agbaye.

Ajo eleto oro-aje ati isamojuto-ilu ni ase lati se idari ilana akitiyan Ajo agbaye to dale awon eto ise ti Igbimo Gbogbo-gboo Ajo fi lole, bii ajo Unicef ati ile-ise alase to n ri si oro awon to wa ni ibi afiwo; ati awon ajo akanse bii ajo to n ri si eto ilera lagbaye (WHO) tabi Ajo awon osise agbaye. Awon Ajo akanse wonyi je olominira ti won ni eto isuna ti won, olu-ile ise won ati awon omo egbe. Ajo eleto oroaje ati isamojuto le fenu adeun ko laarin ara won, ti yoo mu ki ajosepo akanse ise fi wa laarin won ati ajo Isokan agbaye. Ni bayii, ogbon eto ise ati awon ajo akanse ise lo wa lorii eto ilana ajo isokan awon orile-ede agbaye to gbooro. Apapo won lowo si gbogbo akitiyan eda eniyan, ati eto idagbasoke, bere lati oro awon to wa ni afiwo titi kan itaja-raja ati eto nina oju ofurufu

Ni asu karunun odun 1994, akowe Gbogbo-gboo te ijabo kan jade ti a mo si "Oro agbeyewo lori idagbasoke", ti o so o di mimo pe wiwa idagbasoke gbodo pin si aimoye ona, ki o si lowo alaafia, oro-aje, ayika, isedajo ododo ati isakoso awa-ara wa ninu. Eka meji to tun je afikun, je erongba awon omo egbe Ajo ati aba ti Akowe Gbogbo-Gboo gbe kale. Akowe naa wa fi yeni pe eto idagbasoke je ohun pataki kan to n koju omo-eda. "Beeni a n gbagbe ojuse wa lorii sisare tete fun wiwa alaafia ati ifese rinle lori isokan omo-eda". Lai nan-an-ni ise idagbasoke to koju wa

## 14 Kini Ipinnu wi lori awon agbegbe ti ko tii di olominira?

Apa kokanla, kejilọ ati iketala soro nipa awon agbegbe ti won ko tii le da duro tabi di olominira. Apa kokanla kun fun alaye lori awon agbegbe ti ko tii di olominira, ti o si n la kaka lati gba ominira fun awon eniyan to n gbe ni iru agbegbe bayi pelu eto oselu, eto eko ati idagbasoke awon ohun amuludun ni awon agbegbe yii.

Awon omo egbe Ajo mo ririi ipo ti awon eniyan agbegbe bayi wa, ti won si n la kaka lati wa igbe aye rere fun won. Labe Atiku keta-le-laadorin Iwe Ipinnu toka si ipo ti awon eniyan to n gbe orile-ede ti ko i tii di olominira wa, ti won si gba lati maa gbe iwadi lori won sowo si Akowe Gbogbo-gboo lorii eto oro-aje, ohun amuludun ati ipo eto eko ni awon agbegbe naa.

Won da Igbimo alajumo-sepo sile labe Apa ketala lati maa se amojuto labe eto akoso ati abojuto Ajo Isokan Agbaye. Awon ile to wa labe abojuto kii se ile olominira, sugbon won gba lati wa labe ilana abojuto yii laarin awon alase won ati Ajo Isokan Palau. Ni nnkan bii aadota odun sehin ni ilana eto yi ti kase n le pelu Erekusu Palau to gba ominira ninu osu kewa odun 1994 labe akoso Ajo Isokan orile-ede Agbaye.

> Ninu odun 1960, Igbimo Gbogbo-gboo fowo si fifun gbogbo orile-ede to wa labe ijoba ajeji ni ominira ki awon eniyan le bo labe ijoba amuni-sin, niwon igba ti eto ijoba alabojuto ko ju mokanla lo ti opo ile si wa ni kaakiri agbaye. Iko igbimo kan je jade lati se eto gbigba ominira fun awon orile-ede ti ko ni. Lori e, o le ni orile-ede aadorin pelu awon eniyan won to to milionu aadota-le-leedegberin ti won gba ominira, ti won si darapo mo Ajo Isokan Agbaye.

## 15 Kini Ipinnu so nipa Olu-ile-ise?

Iwe Ipinnu fi Olu-ile-ise si ipo pataki kan ninu Ajo Isokan orile-ede Agbaye (wo ibeere Karun lehin) Atiku keta-din-logorun so pe, olu-ile-ise maa ni Akowe Gbogbo-gboo ati awon osise ti Ajo ba fe. Atiku ogorun so pe, osise kan kan ko le gba ase lowo ijoba kankan. Beesini awon orile-ede to je omo egbe ko gbodo gbe igbese lati lo osise fun anfaani ara won lenu ise won. Ko si alaye kanakn lori isakoso Olu-ile-ise. Awon osise to poju owo lagbaye ni won gba senu ise ni Olu-ile-ise tabi awon omo egbe osise ti won n sise won labe Akowe Gbogbo-gboo ati fun anfaani awon omo Egbe Ajo, o fere to egberun lona mokan-din-logbon awon osise Olu-ile-ise Ajo Isokan Agbaye to wa ni kaakiri agbaye. Iko awon Asoju oni koko ise kookan wa, ti o fi je pe apapo awon osise Ajo Isokan Agbaye le die ni egberun lona aadota.

## 16 Awon Atiku wo ninu Ipinnu lo so nipa ojuse Akowe Gbogbo-gboo?

Atiku keta-din-logorun fun Akowe Gbogbo-gboo ni ipo oga agba Alakoso Ajo yii pelu ojuse eto akoso Olu-ile-ise.

Atiku keji-din-logorun kesi Akowe-Gbogbo-gboo lati ma a jabo eto ise Ajo ni odoodun. Ilana yi fun Akowe ni anfaani lati gbe awon koko ojuse Ajo siwaju won ati lati to won sona lori awon ohun to se koko lati muse nise.

Atiku kokan-din-logorun fun Akowe Gbogbo-gboo laye lati gbe ohun yowu to le dena tabi se akoba fun alaafia ati aabo Agbaye siwaju Igbimo Eleto Aabo lori ero tire.

Fun apeere, nigba ti rogbodiyan ile kongo (Congo) be sile ninu odun 1960, Akowe Gbogbo-gboo Dag Hammarskjold gbe oro naa siwaju igbimo Eleto Aabo, labe agbara to ni ninu Atiku kokan-din-logorun fun igba kini. Bakanna ni Akowe Gbogbo-gboo Javier Perez de Cuellar tun lo Atiku yi kanna ni odun 1989 lori isele ni ile Lebano (Lebanon).

## 17 Kinni Ipinnu so nipa ilana ati agbekale iwe Isuna Ajo Orile-ede Isokan Agbaye?

Gege bi alaye lati abala keta-din-logun ninu iwe Ipinnu naa, ojuse Igbimo Gbogbo-gboo ni lati sagbeyewo ati fifi owo si iwe eto isuna. Onikaluku awon orile-ede ti won je omo Ajo naa ni yoo ko ipa tire si ipese owona Ajo Eleto Isokan Agbaye gege bi Igbimo Gbogbo-gboo ba se laa sile.

Igbimo eleto owo kikojo to je eka kan lara Igbimo Gbogbo-gboo ni won pa lase lati sise lori ilana agbeyewo awon orile-ede ti won je omo Ajo naa. Bi agbara awon orile-ede to je omo Ajo ba se to nipa owo sisan ni ojuse won yoo se po to. Eyi ti won gbe le iwon nipa bi owo se n wole fun orile-ede si, ati bi eniyan re se po to.

Lara Ipinnu Igbimo Gbogbo-gboo lodun 1972 ohun ti won fi enu ko le lori ni pe ida meedogbon owo to ba wa ninu iwe isuna ni eyi to tobi julo ti orile-ede kan lee gbe kale, bee sini owo to kere julo ti orile-ede kan lee san ko din ni ida kan ninu ogorun.

## 18 Kinni o le sele ti awon orile-ede ba kuna lati bowo fun ilana Ipinnu Ajo yii?

Ti awon orile-ede ba kuna lati bu ola fun Ipinnu egbe tabi ase eka Ajo Isokan Agbaye, egbe le gbe igbese yowu to ba ye gege bi ese naa ba se tobi to.

Orile-ede to ba kuna lati san eje re sapo egbe, a so eto ati anfaani re nu lati dibo Igbimo Gbogbo-gboo ninu ti owo ti won je naa ba to owo to ye ki won san fun odun meji. Sugbon ti igbimo Gbogbo-gboo ba ri idi pataki ti iru orile-ede bee ko se sanwo, bi apere "Ajalu nla" Won lee yonda iru orile ede bee lati dibo. Sugbon won ko i tii mu lilo abala ofin yi lokunkun dun.

Ti orile-ede kan ba tapa si adeun alaafia tabi o gbe agbere tabi o ko lati bowo fun Ipinnu Igbimo Eleto Aabo eyi to lee da wahala sile lagbaye, o see se lati da seria fun iru orile-ede bee gege bi ohun ti ipinnu naa la sile ni Apa keje, ninu Ipinnu (wo ibeere kesan).

Ti awon orile-ede ba tapa si ofin eto omo-eda, Igbimo alakoso oro eto omo-eda ati oro aje ohun eto ilu lo ni ojuse lati joko jiroro ni pa re.

Igbimo alabojuto eto omo-eda' yan ti won da sile lati maa boju to eto omo-eda lagbaye labe eto omoni' yan ati Igbimo agbaye ti odun 1996 to n ri si eto ilu ati iselu ni anfaani lati topinpin. Lodun 1993, in Igbimo Eleto Aabo agbaye se agbekale Ile ejo agbaye kan lori ogun kiko ja ilu ni ile Yugoslavia atijo (wo ibeere kesan).

Yato si igbagbo awon eniyan, Ajo Isokan Agbaye ko lagbara lati fa orile ede korile ede lo si ile ejo agbaye(ICJ ) latari ai bowo fun Ipinnu naa. A le gbe awuye wuye laarin orile ede meji lo si ile ejo agbaye (ICJ) Ajo agbaye si le gba imoran latodo ile ejo agbaye bakanna. Alaga meedogun ni Ile Ejo agbaye je eyi ti o je pe Adajo meedogun ni won n joko dajo nibe. Odun mesan si ni okookan won nlo ni ipo adajo naa.

Ifara da ati igbagbo awon orile ede ti won je omo egbe lo se okunfa aseyori atiku karun Ipinnu egbe yii, eyi ti o laa sile lati gba omo egbe kale lowo idun ma huru eka Eleto Aabo agbaye. Yiyo bi eni yo jiga lègbe ni igbese to buru ju ti ẹgbe lee gbe, eyi a si ka awon orile ede kan ti won nife ikoja aye won lowo ko. Iyi ti o wa nibe ni pe awon orile-ede ti won je owo egbe ri ara won gege bi omo egbe Ajo agbaye, won si gbodo huwa pele eyi ti ko ni tapo si aala won; ki won si maa se ojuse won pelu.

## 19 Nje Ipinnu fi aaye sile fun orile ede kan lati yo ara re kuro ninu egbe tabi ki egbe yo o labe eto Isokan Agbaye?

Gege bi atiku kefa Ipinnu egbe se wi; omo egbe Ajo Isokan Agbaye ti o ba ta ese agere si Ipinnu egbe , ti iko Eleto Aabo Agbaye ba si fi esun kan-an, le di eni ti Igbimo Gbogbo-gboo n yo legbe. Sugbon sa, lati igba iwase Ajo yii, ko si eni ti won tii yo legbe.

Amo, won ko faye gba awon orile ede kan lati kopa ninu ise Igbimo Gbogbo-gboo (General Assembly). Awon orile ede toro naa kan ni Guusu Afirika odun - 1974-1994, ati Ile Olominira Yugoslavia (Serbia ati Montenegro) lati odun 1992. Igbimo Gbogbo-gboo (General Assembly) si le da oro yi ro nigba kuu gba.

Aye ko si fun yiyo ra eni legbe ninu Ipinnu. Ile Indonesia kuro legbe Ajo Isokan Agbaye ni odun 1965 o si wo egbe pada ni odun ti o te lee.

## 20 Nje o see se lati satunse si Ipinnu, ati pe se o ti sele bee ri?

Atunse lee waye lori Ipinnu gege bi o se wa ninu atiku keji-din-laadofa. Atunse gbodo waye bi idameji ninu meta awon omo egbe Ile Igbimo Gbogbo-gboo ba ti fowo sii. Ida meji ninu meta awon omo egbe pelu awon orile-ede alagbara to wa ninu Igbimo Eleto Aabo le se atunse ti won ba ti gbe awon igbese to ye lati fi se atunse yii labe ilana akosile eto iselu Ajo yii.

Igba meta otooto ni atunse ti de ba Ipinnu yii lati se imugbooro omo Igbimo Eleto Aabo ni odun (1965) ati ti omo Igbimo Eleto Oro-aje ati igbe laruge awujo ninu odun (1968 ati 1973).

## 21 Iru akitiyan wo lo n lo lowo fun agbeyewo awon ilana Ipinnu naa? Nje ijiroro kankan ti waye fun ayipada ilana igbaniwole omo egbe ati ibo didi ninu igbimo Eleto-Aabo?

Awon orile ede ti won je omo Ajo ti bere ijiroro lori pataki ipinnu nipa bi ile aye se n yi pada lati akoko idasile Ajo Isokan agbaye. Lodun gbooro seyin, eka kan lara Igbimo Gbogbo-gboo ti fon ipe si Igbimo Akanse lori ipinnu Ajo Isokan Agbaye ati lori wiwa agbara kun agbara ojuse Ajo naa, eyi ti won ti gbe oniruuru ojuse fun nipa sise agbeyewo awon ipese ohun ilana ipinnu yii.

Lodun 1992, Igbimo Gbogbo-gbo lo tewo gba ojuse akojo awon omo Igbimo Eleto Aabo. O gba pe looto ni igbe aye n yi pelu bi omo egbe Ajo naa se n po sii.
Igbimo Gbogbo-gboo so fun awon orile ede ti won je omo Ajo naa lati

mu ero won nipa abala kookan ninu iwe Ipinnu lo si iwaju Akowe Gbogbo-gbo. Lara iru awon akiyesi bee ni, amugbooro ati pinpin omo Igbimo ni dogbandogba ninu Igbimo Eleto abo. Awon orile ede ti won je omo Ajo ti fi ife han si amugbooro awon omo egbe loore-koore ati awon omo egbe naa ti agbara ipase wa lowo won ati fun awon orile ede yato si awon marun pere ti won je omo Ajo naa.

Bakanna ni won tun fi ife han si atunto awon abala miran ninu Igbimo Eleto-Aabo, bii ilana ibo didi, akoyawo nipa ajosepo igbimo yii pelu eka yoku, papaa julo, Igbimo Gbogbo-gboo. Odun 1993 ni Igbimo se agbekale igbimo amuse se kan lati foju sunnukun wo omo egbe pinpin dogba-n-dogba ati amugbooro awon omo Igbimo Eleto Abo yii.

## 22 Nje Ipinnu yii wulo laarin odun melo kan sehin?

Won ti n so pe Ipinnu yii je jade lori isele to di ogun Agbaye keji, nitori idi eyi ko wulo fun ipo ti agbaye wa ati awon rogbodiyan to n waye lehin senturi ogun.
Sugbon sa awon omo egbe Ajo, Isokan Agbaye toka sii pe Ipinnu je adeun to ye ko waye ti a si le tumo pelu irorun fun lilo wa eyi ti o faye gba eto idagbasoke ojo iwaju. Daju-daju aaye wa fun atunse to ti waye ri, ti yo si tun maa tesiwaju lojo iwaju.

Ipinnu yii ti wa fun aadota odun, ati pe pelu suuru laarin awon omo egbe, Ipinnu yi a maa tesiwaju lati pese awon idi pataki to fi waye.
Ipinnu yi je ise ajumose po ti kii se ohun ti a kan dede ko sile. Nipa amulo re ati ireti ti a ni fun ojo iwaju ni agbara re wa.

**Awon iwe ilewo fun kika.**

Iwe Ipinnu Ajo Isokan Orile-ede Agbaye (fun tita)

- Awon eto ilana fun alaafia pelu akokun re( fun tita)
- Eto ilana fun idagbasoke (fun tita)
- Ajo Isokan Orile ede Agbaiye ni soki.
- Irisi ati ifarahan
- Awon ohun to se koko nipa Ajo Isokan Agbaye (fun tita)

**Fun alaye kikun kan si**

Ibudo Eto Iroyin Ajo Isokan Agbaye nitosi re tabi ni

**Eka Iyara Iwadi GA - 57**
**UNITED NATIONS**
**NEW YORK, NY 10017**

**Fun awon eroja tita, kan si**

**United Nations Publications**
**Room DC2 - 853**
**New York, NY 10017 tabi**
**United Nations Publications**
**Sales Office and Bookshop**
**CH - 1211 Geneva 10, Switzerland.**

Published by the United Nations Information Centre
17, Kingsway Road, Ikoyi, Lagos, Nigeria.
DPI/1738-13403-November 2000